# IROHIN YORUBA

L... ... wa—"IWAJU L'OPA EBITI ... E S..."

V..., IX NO. 425 — MONDAY NOVEMBER 9 1953 — KOBO KAN (1d)


## Oloye Salami Agbaje Ku

IBADAN—Ni ojo Eti ti ise (gbese') ose ti o koja yi ni Oloye Salami Agbaje, Balogun Ibadan ti aiye sile ni ile re nigbati o di eni odun marundinlogorin lehinti o ti se aisan fun osu die, nwon si sin oku re ni ojo keji ti o ku ninu ile re na, ni ona ti Musulumi fi n sin oguniogo awon enia pataki pataki. Imam Mudi, Oga gbogbo awon Lemomu ilu ti Mosalasi Jimo l'Ojaba ni o se sin isinku na, awon lemomu keekeeke si ran an lowo. Dokita S. Agbaje ti ise Dawodu Ologbe na ati awon aburo re si pese sibi isinku na.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon ti o wa ibi oku na ni Dokita S. O. Biobaku, (Registrar University College, Ibadan), Ogbeni C. D. Akran (Minister for Local Development), Dokita Sodipo, Hadji Jibril Martins, Dokita Johnson, Olola Abiodun Akerele M.H.A. Oloye Salawu Aminu, awon Ogbeni Akinpelu Obisesan, S. O. Lanlehin, awon Loya Olayinka Odumosu, A. Olukoya, E. Akin Cole, Adaje Ogbeni ati Iyaafin Adeyinka Morgan, Oloye Bello Abasi, Oloye Okumola, awon Olola E. A. Sanda, R. O. Makanjuola ati S. A. Ojoko.

Die ninu awon omo ti Ologbe na fi si aiye lo ni Dokita A. S. Agbaje, awon Loya Ganiyu ati Mojidi Agbaje, Hadji Agbaje awon Ogbeni Jacob ati Ramonu Agbaje. Ki Olorun darijin oku na, ki O si je ki ehin re dara o.



OLOGBE OLOYE SALAMI AGBAJE

### Layekaye Yoruba Lo Ni Ilu Eko

## Mo Ki Olotu Ku Orire

### Lati Owo Samuel Idowu Ajihinrero—EKO

NI ojo Abameta ti ise ojo kokanlelogbon osu kewa odun yi ni Ogbeni S.M. Ademuyiwa Olotu Irohin Yoruba ri waya gba lati Eko nibiti o ngbe nse oku egbon re ni Abeokuta pe Iyawo re, Iyaafin Felecia Taiwo Ademuyiwa bi omokunrin kan ni ile itoju awon omotitun (Mercy Dispensary) ni Ita Eleye lona oja Ita Faji. Bi Olotu ti mba gbogbo awon onkawe Irohin Yoruba yo, a dupe pe Olorun si fun awa onkawe Irohin Yoruba paapa laye nisisiyi lati ba on na yo ayo omo-kunrin ti Olorun yonda fun on ati aya re na. A si fi ife ati ayo ki omo titun "IDOGBE" na (nitori a bi i le Al..ba ni) ku ewu irin ajo. Ki Olorun da a si ki O si se e ni omo olorire, a si be Olorun ninu anu Re lati ba ni toju re pe bi o ti ndagba li odun ki o si le ma a bi si ni ogbon ki o si le ma a ri ojurere Olorun ati t'enia. Olotu Tiwa Owon, E ku ewu o, e si ba ni ki Iyawo pe nwon ku owo l'omi o.

## Oye Esa Di Ijongbon Ni Ilu Oba-Ile

OBA—'LE VIA OSOGBO—Lehin iku Oloye Esa Folarin ti Ile Oraaru ni Ilu yi, ni ijangbon kan be sile lori eniti yio dipo re. Alaiyeluwa Oba Ile yi faramo o wipe ki Ogbeni Omisade eniti ise aburo Folarin ti o ku ko dipo re, sugbon gbogbo awon ijoye ati awon ti o usanwo ori pelu Egbe Atanluse l'oke kori wipe iwa Oba yi ki ise eyiti o to aza ilu lorun ati wipe o si lodi si asa ati eto Esa jije ni ilu yi. Nwon fi enu sokan wipe ile mej ni o nje Oye yi gege bi isedale, torina Ogbeni S. Oyaniran ti ile keji ti o nje oye yi ri ni o ni lati dipo Folairo ti o ku.

Titi di asiko ti a nkowe yi, awon ijoye ati Oyemboge Omo ilu ko si ni dede pelu Oba won mo. Awon ipade nla fun Eto ilu (Executive Committee) ti Oshogbo gbiyanju lati dasi oro na, sugbon awon omo ilu ati ijoye ko, awon pinnu wipe Ajele Agba ti "Oshun Division" ni Oshogbo ti nwon ri i pe ko si yera lori oro na ni ki o ba won dasi i. Nwon si ti kowe si Ajele Agba na lori oro na fun atunse.

## Ijoba Ibile Oyo Ko Alafin L'Oba

OYO—Ni ojo Ojobo ti ise ojo kokandinlogbon osu kewa odun yi ni awon Igbimo Ijoba Ibile Oyo, (Oyo Divisional Native Authority Council) se ipade Igbimo ni Gbongan Apejo Atiba. Ogbeni J. Ola Akode da a si imoran pe ki nwon yo Alafin l'oye.

Nwon si gba lati se be e, nwon si tun pinnu ninu ipade Igbimo na pe awon ko fi ara mo iyapa ilu Eko kuro labe Ijoba Iwo-orun Nigeria.

Nwon si yo Ogbeni P. A. Afolabi Oga awon oluko Ile-iwe Aguda l'Eko kuro ninu apejo Igbimo Ijoba Ibile Oyo na. Nwon si tun yan Oloye Bode Thomas Balogun Oyo ni Alaga Igbimo na laisi atako kankan.


## ODUNSI POOLS

5, GRIFFIN STREET, (OLOWOGBOWO)
MAIL BAG, LAGOS

**Win 4 Races In 560 Ways.**

Forecast IN ANY ORDER.

10 Pools On One Coupon, Lowest Stake: 6d

**WIN 3rd DAY**

IBADAN RACES On ODUNSI POOLS.

Apply NOW for FREE RACE COUPON (if over 21).

## REDIFFUSION

FOR LESS THAN THREEPENCE PER DAY
*you can obtain*

NEWS
MUSIC
EDUCATION
ENTERTAINMENT

FROM 6 A.M. to 11 P.M.

IN YOUR OWN HOME

APPLY AT OFFICES IN LAGOS, IBADAN & ILESHA.

